# Àkànlò-èdè Tuntun Nínú Àwọn Orin Ọ̀dọ́ Ìwòyí

Dayọ Akanmu
Adeniran Ogunsanya College of Education
Ọ̀jọ́/Ijanikin, Lagos
dayoakanmu2002@yahoo.com

## Àṣamọ̀

Àkaǹlò èdè Yorùbá tuntun jẹ́ ìpèdè tí Àkànmú (2016) pè ní ìsọ ìgbàlódé tí ìtumọ̀ wọn lọ́ọ̀rìn díẹ̀ tí ó sì ṣàjèjì sí àwọn tí ó máa ń ṣe àmúlò àkànlò èdè ti-wa-n-tiwa tí ó ti wà tẹ́lẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ìwádìí ní ó ti wà lórí ìṣàmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú orin, fíìmù àgbéléwò, ìpolówó ọjà, ìròyìn, ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ nínú eré bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá láàrin àwọn èrò ìwòran ní gbàgede ìwòran àti ìgbòkègbodò ọkọ̀ ṣùgbọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ sí iṣẹ́ tí ó jinlẹ̀ lórí ìjẹyọ àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú orin tàka-súfèé òde òní èyí tó wọ́pọ̀ láàrin àwọn ọ̀dọ́. Akitiyan láti dí àlàfo yìí ní ó bí àpilẹ̀kọ yìí. Tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ (Standard Language Theory) tí Mukarovsky ṣe agbáterù rẹ̀ ni a fi ṣe àtúpalẹ̀ àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí á yẹ̀wò nínú bébà yìí nítorí pé ó lè ṣàlàyé ohun tí ó jẹ́ kí àkànlò èdè Yorùbá tuntun yapa si èdè ojoojúmọ́ àti ohun tí ó ń fa ìyàtọ̀ gíríkì láàrin èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì. A ṣe àṣàyàn ọ̀kọrin tàka-súfèé mẹ́ta wonyi: Olátúnjí Ọládọ̀tun Àlàdé (Dotman), Azeez Fáṣọlá (Naira Marley) àti Oritse Fẹ́mi Májẹ̀ẹ́mitẹ́ Èkélè (Oritsa Fémi) nítorí pé àkànlò èdè Yorùbá tuntun farahàn púpọ̀ nínú orin wọn. Nínú ìtúpalẹ̀ wa ni ó ti hàn pé àwọn ọ̀kọrin tàka-súfèé òde-òní fẹ́ràn láti máa ṣe àmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun bí i 'oúnjẹ ọmọ' (fún obìnrin tí ó ní ọyàn ńlá èyí tí ó bù kún ẹwà a rẹ̀), 'jẹ̀wà' (ṣewọ̀n), 'ojúẹlẹ́gba' (oluko, ará oko èèyàn tàbí ẹni tí ojú rẹ̀ dúdú), 'gbé bọ́dì ẹ' (lo ọpọlọ tàbí ọgbọ́n orí ẹ) àti 'yàúyàhúù' (àwọn tí ó ń fi ẹ̀rọ ayélujára lu jìbìtì) gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àti ìdánilárayá. A ṣe àmúlò àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ fún ìṣẹ̀dá àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí ó jẹ yọ. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ yìí náà ni ó bí ìsọdorúkọ, firósínròòjẹ àti àwọn èròjà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ mìíràn tí a lò nínú àpilẹ̀kọ yìí. Ó hàn gbangba pé àkànlò èdè Yorùbá tuntun rẹwà jù lọ fún ìbáraẹnisọ̀rọ̀, ṣíṣe àlàyé ọ̀rọ̀, àpèjúwe àti ìdárayá nínú orin tàka-súfèé.

# Ìfáàrà

Iṣẹ́ ìwádìí yìí níí ṣe pẹ̀lú ìlanilọ́yẹ wí pé yàtọ̀ sí ojúlówó èdè Yorùbá tí tẹrú-tọmọ ń sọ káàkiri ilẹ̀ káàárọ̀-oò-jíire, àwọn ìsọ tàbí ìpèdè kan tún wà tí a kò kọbi-ara sí bíi ìpèdè amúṣẹ́ṣe, ìpèdè eré ìdárayá, ìpèdè ẹ̀fẹ̀, ìpèdè aṣa àti àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí iṣẹ́ yìí dálé lórí, tí wọ́n sì ní ìtumọ̀ àti ìwúlò wọn ní àwùjọ. Lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé ìmọ̀ nípa ọ̀rọ̀ 'ayé-lu-jára ni ó ṣokùnfà díẹ̀ lára àwọn ìpèdè yìí, lọ́nà tí ó mú ìpèníjà bá àwọn tí ó ń sọ ojúlówó èdè Yorùbá nípa ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tuntun tí a lè lò fún oríṣìí ohun ọ̀tun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àgbáyé. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé bí ohun gbogbo ṣe wà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ kọ́ ni ó rí mọ́ ní òde-òní; ayé ti lajú ju ti àtẹ̀yìnwá lọ. Èyí gan-an ni ó fà á tí àkànlò èdè Yorùbá tuntun ṣe lalẹ̀hù gẹ́gẹ́ bí ìpèdè tí ó ń bù kún ẹwà èdè Yorùbá, tí ó tún ṣe é lò fún àwọn ohun ọ̀tun tí ó ṣàjèjì sí àṣà tiwa èyí tí àṣà àti ètò 'ayé-lu-jára' mú wá sí àwùjọ wa.

Ní àsìkò yìí, ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ẹ̀ka ibi tí ọwọ́jà ètò 'ayé-lu-jára kò dé nínú àṣà àti ìṣe, èdè, ètò ìṣèlú, ètò ẹ̀kọ́, ọrọ̀-ajé, eré ìdárayá àti orin ní gbogbo orílẹ̀-èdè àgbáyé. Nínú gbogbo nǹkan wọ̀nyí, ohun tí ó múmú láyà àwọn ọmọ Yorùbá ní ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti fi ohun tó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́ tó àwọn ènìyàn létí tàbí láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn wọn mọ bí ohun gbogbo ṣe ń lọ káàkiri orílẹ̀ èdè àgbáyé àti láti gbé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ yàjóyàjó tí ó ń wáyé lórílẹ̀ èdè àgbáyé sí etígbọ̀ọ́ wọn. Irú ìpèdè yìí gbayì púpọ̀ láàrin àwọn ọ̀dọ́ nítorí pé kò wà fún ìbánisọ̀rọ̀ nìkan, ó tún wúlò fún ìdárayá. Ìdárayá yìí gan-an ni ó jẹ wọ́n lógún jù, kò sì lè ṣe àkóbá fún ojúlówó èdè Yorùbá nítorí pé òun gan-an ni ó ń jẹ́ kí wọ́n lè máa sọ èdè Yorùbá díẹ̀díẹ̀ tí wọn ń sọ. Ọ̀pọ̀ nínú wọn ni kò gbọ́ èdè Yorùbá rárá bí kò ṣe ti irú orin tàka-súfèé tí wọn ń gbọ́ nípasẹ̀ ètò ayé-lu-jára yìí. Ìdí nìyí tí wọ́n fi gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa ètò ayé-lu-jára gẹ́gẹ́ bí i ti àwọn ẹlẹgbẹ́ wọn ní àwọn orílẹ̀ èdè àgbáyé mìíràn, kí wọ́n sì tún ṣe àmúlò èdè Yorùbá ní ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ sí bí a ti ṣe ń lò ó tẹ́lẹ̀. Ṣíṣe àmúlò èdè Yorùbá ní ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ báyìí ni yóò fi ìdí òtítọ́ múlẹ̀ fún àwọn tí ó lérò pé èdè Yorùbá kò kúnjú òsùwọ̀n tó láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn èrò àti ìṣẹ̀lẹ̀ tuntun pẹ̀lú àwọn ohun ọ̀tun mìíràn tí ó ṣàjèjì sí àṣà àti ìṣe Yorùbá.

Ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí oríṣìíríṣìí èrò àti ìṣẹ̀lẹ̀ tuntun ti ń jáde ní àgbáyé ni orin tàka-súfèé jẹ́ àti pé ìpèníjà ńlá gbáà ni àgbékalẹ̀ irú orin báyìí kọ́kọ́ jẹ́ fún àwọn ọmọ Yorùbá tí ó ń kọ ọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ nítorí pé èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí nígbà mìíràn Píjìnnì ni àwọn tí ó ni orin náà fi ń ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ nítorí pé láti inú àṣà àti ìṣe ilẹ̀ Amẹ́ríkà ní ó ti jẹ jáde.

Ní àsìkò ìṣèjọba àwọn olóógun láàrin ọdún 1985 si ọdún 1990 ni orin tàka-súfèé lalẹ̀hù nígbà tí ohun gbogbo wọ́n bí ojú, tí ara bẹ̀rẹ̀ sí ni ará ìlú. Ìyànjú láti wá ohun tí yóò máa dá àwọn ará ìlú lárayá tàbí mú ara tù wọ́n àti láti wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣe àdá nípa àìríṣẹ́ ṣe ni ó jẹ́ kí àwọn ọ̀dọ́ gba wèrè orin náà gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ títí tí ó fi di ohun tí ó wọnú àṣà àti ìṣe àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yìí, ní pàtàkì jùlọ, àwọn ọ̀dọ́ Yorùbá lónìí. Ìdí nìyí tí kò fi nira fún àwọn ọ̀kọrin tàka-súfèé

àti àwọn tí ó ń ṣe àmúlò èdè Yorùbá lójú méjéèjì láti wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣe àdá nípa ìṣòro èdè tí ó lè wáyé nínú orin náà nítorí pé ọ̀nà àbáyọ sí irú ìṣòro tàbí ìpèníjà báyìí ni a pè ní 'èdè ríro̩'. Gẹ́gẹ́ bí Ọlátẹ́jú (2005:9) ṣe sọ, èdè ríro̩ ni ṣíṣe àgbélẹ̀rọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tuntun àti gbígbé ìtumọ̀ tuntun gun orí ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ tí ó ti wà tẹ́lẹ̀. Lára àwọn onímọ̀ tí ó ti ṣe àfihàn àwọn ọ̀nà pàtàkì tí à ń gbà láti ṣe àgbélẹ̀rọ ọ̀rọ̀ tuntun nínú iṣẹ́ wọn ni onímọ̀ bí i Bámgbóṣé (1992), Ọlátẹ́jú (2005; 2008; 2012), Yusuf (2008) àti Àkànmú (2014; 2016). Àkànlò èdè Yorùbá tuntun ni àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ tí a ṣe àgbélẹ̀rọ wọn ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà èdè tí àwọn onímọ̀ tí a mẹ́nubà síwájú ṣiṣẹ́ lé lórí. Nítorí pé kò sí ibi tí àwọn ìpèdè yìí kì í tí farahàn nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ ni a fi ṣe àyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ wọn gẹ́gẹ́ bí ìlò èdè tuntun tí ó wà nínú orin tàka-súfèé tí àwọn ọ̀dọ́ òde ìwòyí ń kọ.

## Kín ni Orin jẹ?

Àjànàkú ni ọ̀rọ̀ orin jẹ́, ó ti kúrò ní mo rí nǹkan fìrí, tí a bá ti rí erin, ká gbà pé a rí erin. Ọ̀kan pàtàkì nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá èyí tí ó so mọ́ ètò ìgbé ayé wọn ni orin jẹ́. Kárí ayé ni ọ̀rọ̀ orin jẹ́, bẹ́è sì ni kò sí ibi tí a kì í tí dáná alẹ́ ni ọ̀rọ̀ orin jẹ́, ọbẹ̀ yóò kàn dùn ju ara wọn lọ ni. Kò sí ibi tí a kì í tí kọrin lókè eèpẹ̀, orin kàn máa yàtọ̀ síra wọn ni, ìyàtọ̀ orin lè jẹ́ nípa ti èdè àti àgbékalẹ̀ rẹ̀ àti ìgbà tí a máa ń kọ ọ́.

Iṣẹ́ ti pọ̀ lọ jàrá lórí ohun tí orin jẹ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn onímọ̀ bí i Ọlátúnjí (1984), Àlàbá (1992), Adégbìtẹ́ (1995), Agbájé (2013; 1995), Kúkọ̀yí (1995), Adédèjì (2004), Dáramọ́la (2008), Ajíbádé (2011), Ọmọ́jọlà (2017), àti Ọ̀jó pẹ̀lú àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ (2018). Oríṣìí èrò ni àwọn onímọ̀ yìí gbé kalẹ̀ nípa orin, àwọn kan rí orin gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ewì alohùn nígbà tí àwọn mìíràn rí orin gẹ́gẹ́ bí ohun tí a fi ń ṣètò ìlú, ohun tí a fi ń túnwà ara ẹni ṣe, ohun tí a fi ń gbé èrò ọkàn wa jáde àti ohun tí a fi ń dáni lára yá.

Gbogbo èrò àwọn onímọ̀ yìí lórí orin ni ó ṣe wẹ́kú pẹ̀lú èròǹgbà bébà yìí nítorí pé àwọn olórin tàka-súfèé ń lo àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú orin wọn láti gbé èrò ọkàn wọn jáde àti láti dá àwọn olùgbọ́ wọn lárayá ni.

## Orísun Orin Tàka-súfèé

Kò yẹ kí á ṣẹ̀ṣẹ̀ máa sọ pé orin tàka-súfèé ṣe àjèjì sí àṣà àti ìṣe àwọn Yorùbá ṣáájú àkókò yìí. Orin tàka-súfèé jẹ́ ẹ̀yà orin kan tí orísun rẹ̀ wá láti ibi àríyá ì-gba-fàájì àwọn ènìyàn dúdú (black parties) ti ìlú New York, ní pàtàkì jùlọ, àwọn tí ó ń gbé ní àdúgbò kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Bronx, ní ilẹ̀ Amẹ́ríkà. Àdúgbò tí a pè ní Bronx yìí ni a gbọ́ pé àwọn ènìyaǹ dúdú Amẹ́ríkà pọ̀ sí dáadáa. Orísun orin tàka-súfèé yìí gan-an ni a tọ ipasẹ̀ rẹ̀ lọ sí ọ̀dọ̀ arákùnrin a-sọ̀rọ̀-di-orin (Rapper) kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Keith Cowboy tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ikọ̀

ọ̀kọrin Amẹ́ríkà kan tí a pè ní Abínú kọrin márùn-ún (The furious five) èyí t́i DJ Grandmaster jẹ́ olórí wọn (Keyes, 2009).

Ọdún 1970 síwájú díẹ̀ ni orin yìí bẹ̀rẹ̀ ní ìlú NewYork ṣùgbọ́n ní ìparí ọdún 1980 sí ìbẹ̀rẹ̀ ọdún 1990 síwájú ni ó bẹ̀rẹ̀ sí ní lalẹ̀hù tí ó sì ń gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ìlú Èkó ni ó ti kọ́kọ́ bẹ̀rè lásìkò ìjọba Ológun nígbà tí gbogbo nǹkan bẹ̀rẹ̀ sí ní gbówó lórí, tí ara sì ń ni àwọn ará ìlú. Ìyànjú láti pa ìrònú rẹ́ àti láti dá àwọn ènìyàn lárayá ni ó mú kí àwọn ọ̀dọ́ ìgbà náà gbé igbá orin tàka-súfèé (Lamidi, 2011). Láti ìgbà yìí lọ, kò sí ibi tí a kì í ti ́gbúròó orin tàka-súfèé tí àwọn ọ̀dọ́ ń kọ lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti pé tọmọdé tàgbà ló ń gbọ́ orin náà. edè Gẹ̀ẹ́sì àti Píjìnnì Amẹ́ríkà (Píjìnnì Amẹ́ríkà ni èdè Gẹ̀ẹ́sì orílẹ̀-ede Amẹ́ríkà tí kò pójú owó gẹ́gẹ́ bí èdè Gẹ̀ẹ́sì ojoojúmọ́ tí ó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà fún gbogbo ará ìlú irú èyí tí wọ́n ń sọ ní orílẹ̀-èdè England) ni orin yìí bá wọ ilẹ̀ Adúláwò ṣùgbọ́n èdè Gẹ̀ẹ́sì, Píjìnnì àti èdè abínìní tiwa ni àwọn ọ̀kọrin tàka-súfèé òde-òní ń lò jù. Iṣẹ́ ọpọlọ àti àtinúdá tó yanrantí ni àwọn ọ̀kọrin yìí fi ń gbé orin wọn kalẹ̀. Fún ìdánimọ̀ àti kí àwọn ènìyàn lè mọ ìyàtọ̀ tó wà láàrin wọn àti àwọn ọ̀kọrin mìíràn àti kí wọ́n lè jèrè owó gọbọi nínú iṣé orin tàka-súfèé yìí ni àwọn tí ó jẹ́ ọmọ Yorùbá nínú wọn ṣe ń fi èdè Yorùbá bọ inú orin yìí lóòrè-kóòrè. Ilé ìjọsìn ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn ti kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ orin ṣùgbọ́n nígbà tí wọ́n rí i pé orin ìyìnrere kò fi bẹ́ẹ̀ mú owó wọlé bíi ti tàka-súfèé èyí tí àwọn ọ̀dọ́ nífẹ̀ẹ́ sí jù, tí ó sì tún fi àyè gbà wọ́n láti kọ orin tó bá wù wọ́n ni ó sọ wọ́n di ọ̀kọrin tàka-súfèé. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n kọ́kọ́ ń fi gbé orin yìí kalẹ̀ nígbà tó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀, àwọn ọ̀kọrin tí ó jẹ́ ọmọ Yorùbá yìí kò gbàgbé orísun wọn ni wọn ṣe ń lo àmúlùmọ́là èdè Gẹ̀ẹ́sì, Píjìnnì àti Yorùbá láti fi ṣe àkọsílẹ̀ àti àgbékalẹ̀ orin wọn. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ó lè jẹ́ kìkìdá Yorùbá ni wọn yóò fi ṣe àgbékalẹ̀ apá kan nínú orin wọn (Elugbe 2012).

Ṣíṣe àmúlò èdè Yorùbá nínú orin tàka-súfèé yìí tún jẹ́ ohun tí ó fi ni lọ́kàn balẹ̀ wí pé èdè Yorùbá kò lè sí lára àwọn èdè tó ń dákú-dájí tàbí èdè tí yóò kú ní ọjọ́ iwájú. Ìdí ni pé, orin tàka-súfèé ti wọnú àṣà àti ìṣe wa lọ́jọ́ tòní. Tẹrútọmọ ló ń kọ ọ́ báyìí, a sì rí ẹ̀yà mìíràn tí wọ́n gbọ́ Yorùbá tí wọ́n sì fẹ́ràn láti máa kọ irú orin yìí; bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn tó jẹ́ òyìnbó àti ọmọ ilẹ̀ Ìgbò tí kò gbọ́ èdè Yorùbá tí ń tipasẹ̀ gbígbọ́ orin yìí kọ́ èdè Yorùbá. A rí àpẹẹrẹ ọmọ Ìgbò kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Chukwuka Jude tó tó ẹni bí ọmọ ọgọ́ta ọdún tó sọ orin tàka-súfèé tí a fi èdè Yorùbá kọ di ohun tí gbogbo ènìyàn ń gbọ́ nígbà tó bá ń dá kọ ọ̀kan-ò-jọ̀kan orin yìí lórí àwọn ohun èlò ìgbéròyìnjáde bíi 'yútuubù'. Àkíyèsí ìtànkálẹ̀ àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú orin tàka-súfèé yìí gan-an ni ó ṣokùnfà àpilẹ̀kọ yìí.

## Bí a ṣe gba Détà

A gbé iṣẹ́ ìwádìí wa lóri àwọn gbajúgbajà àti ìlú-mọ̀-ń-ká ọmọ bíbí ilẹ̀ Yorùbá tó jẹ́ akọrin tàka-súfèé mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nínú ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn olórin tàka-súfèé

tí ó wà lóde. A ṣe àṣàyàn àkànlò èdè Yorùbá tuntun mẹ́rin, mẹ́rin nínú orin Ọlátúnjí Ọládọ̀tun Àlàdé (Dotman) tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ 'Ẹnú Gbẹ', Azeez Fáṣọlá (Naira Marley) tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ 'As E Dey Go' àti Oritse Fẹ́mi Májẹ̀ẹ́mitẹ́ Ekele (Oritse Fẹ́mi) tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ 'Ó ń Gbá Lára Mi' gẹ́gẹ́ bí àwọn orin tàka-súfèé tí àkànalò èdè Yorùbá tuntun sodo púpọ̀ sínú wọn. Orí ẹ̀rọ Yútuùbù ni a ti gba àwọn orin yìí sílẹ̀ fún ìtúpalẹ̀ èyí tí a fi ìlànà ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè gbé kalẹ̀ lọ́nà tí ó ṣe àfihàn wí pé àwọn olórin tàka-súfèé ń ṣe àmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun fún àgbọ́yé àti ìdárayá àwọn olùgbọ́ wọn.

## Èrò Àwọn Onímọ̀ Lóri Àkànlò Èdè Yorùbá Tuntun

Àkànlò èdè Yorùbá tuntun dàbí ilẹ̀ ọlọ́ràá tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe àwárí rẹ̀ tàbí tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ fara hàn fún irúgbìn ṣùgbọ́n tí àwọn ènìyàn kò tí ì kọbi ara sí . Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé àwọn onímọ̀ tó ṣiṣẹ́ lórí àkànlò èdè Yorùbá tuntun kò tí ì fi bẹ́ẹ̀ pọ̀ rárá ṣùgbọ́n iṣẹ́ ti wà lórí 'àgbélẹ̀rọ èdè' (coinages) gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ọ̀nà tí à ń gbà ṣẹ̀dá àkànlò èdè Yorùbá. Àwọn onímọ̀ bí i Bámgbóṣé (1992), Ọlátẹ́-jú (2008;2012) Yusuff (2008) àti Babalọlá (1972) tí sọ pé ṣíṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tàbí ṣíṣe àgbélẹ̀rọ (neologism) ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ọ̀nà tí à ń gbà láti gbé èrò tuntun tàbí nǹkan tuntun gorí àwọn ìmọ̀ tàbí ìṣe tí ó ṣàjèjì sí àṣà àti ìṣe ilẹ̀ wa. Ṣíṣe àg-bélẹ̀rọ àti àgbélẹ̀rọ èdè kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ síra wọn, àwọn méjèèjì ló dá lórí ṣíṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun, ó kàn jẹ́ pé, ní ọ̀pọ̀ ìgbà tí a bá ṣe àgbélẹ̀rọ èdè, a máa ń gbé ìtumọ̀ tuntun gun orí ọ̀rọ̀ tuntun tí a ṣẹ̀dá rẹ̀ ni.

A tún ṣe àkíyèsí pé kò fi bẹ́ẹ̀ sí iṣẹ́ gíríkì lórí àkànlò èdè tiwa-n-tiwa tí a ti mọ̀ tẹ́lẹ̀ saájú àkókò yìí àyàfi àwọn onímọ̀ tí wọ́n kàn mẹ́nubà á léréfèé àti àwọn tí wọn kàn ṣe àkójọpọ̀ oríṣiíríṣìí àkànlò èdè Yorùbá. Àwọn onímọ̀ yìí rí àkànlò èdè àtijọ́ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tí ìtumọ̀ wọ kò lọ tààrà tí kò sì rọrùn láti tú ní ẹyọ ọ̀rọ̀ sí ẹyọ ọ̀rọ̀, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, a ó sọ ìtumọ̀ wọn nù nítorí pé àgbékalẹ̀ alákànpọ̀ ọ̀rọ̀ ni ìṣẹ̀dá àti ìrísí ọ̀kọ̀ọkan wọn.

Ìwọ̀n ìba àwọn onímọ̀ tó ṣiṣẹ́ sàn-án lórí àkànlò èdè Yorùbá tuntun ni Àkàn-mú (2020; 2019; 2018; 2017; 2016; 2015; 2014) àti Ọlátẹ́jú (2005; 2016). Ní ìbámu pẹ̀lú kókó inú àpilẹ̀kọ yìí, àwọn onímọ̀ yìí rí àkànlò èdè Yorùba tuntun gẹ́gẹ́ bí ìlò èdè tuntun tí ó jẹ jáde nípasẹ̀ ìdíwọ́ tàbí ìṣòro èdè tí ó ń kojú àwọn tí ó ń ṣàmúlò èdè Yorùbá tuntun nígbà tí wọ́n bá fẹ́ gbé òye tàbí èrò tó ṣàjèjì sí àṣà ilẹ̀ wọn jáde. A rí wọn gẹ́gẹ́ bí àkànlò èdè tuntun nítorí pé wọ́n yapa díẹ̀ sí àkànlò èdè àtijọ́ nítorí pé ìtumọ̀ wọn lọ́ọ̀rìn díẹ̀, àgbékalẹ̀ wọn sì fara pẹ́ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àfidípò, àti àkànlò èdè àtijọ́ ní ti ìhun àti ìtumọ̀. Àkànlò èdè Yorùbá tuntun ṣe é sọ lẹ́nu, ó sì ṣe é kọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ti àtijọ́, bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n tún lè dúró gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀. Àwọn èèyàn nínú àwùjọ tí ó ń sọ èdè Yorùbá náà ni ó ṣẹ̀dá wọn, ìdìdélẹ̀ wọn kò ṣàjèjì sí àwọn tí ó ń ṣàmúlò wọn. Àkànlò èdè Yorùbá tuntun jẹ́ ìpèdè tàbí ìsọ tí a ṣẹ̀dá wọn nípa ṣíṣe àgbélẹ̀rọ (coining) ọ̀rọ̀ tuntun tàbí nípa gbígbé ìtumọ̀ ọ̀tun gun orí àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀

tí ó ti wà tẹ́lẹ̀ nínú èdè Yorùbá. Àkànlò èdè Yorùbá tuntun ti di ìpèdè tàbí ìsọ tí a máa ń bá pàdé lóòrèkóòrè nínú ìsọ tàbí èdè ojoojúmọ́ àti nínú ìwé tí a kọ.

## Tíọ́rì Èdè Ojoojúmọ́

Tíọ́rì àmúlò fún iṣẹ́ yìí ni Tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ (Standard Language Theory) tí Mukarovsky (1970) ṣe agbátẹrù rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí tíọ́rì tí ó pegedé, tí ó sì fi gbọ̀ọ̀rọ̀ jẹkà láti ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé nípa ìyàtọ̀ gíríkì tí ó wà láàrin èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì. A yan tíọ́rì yìí láàyò nítorí pé ó lè sọ àsọyé lórí ohun tí ó ń fa ìyapa àkànlò èdè tuntun sí èdè ojoojúmọ́ àti bí àkànlò èdè Yorùbá tuntun ṣe jẹ́ ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun. Mukarovsky (1970) rí èdè ojoojúmọ́ gẹ́gẹ́ bí èdè tí a fi ń bára ẹni sọ̀rọ̀ lójoojúmọ́ àti nígbà gbogbo láàrin aṣafọ̀ àti òsùnsùn afọ̀ fún àsọyé àti àgbóyé ọ̀rọ̀. Èdè ojoojúmọ́ lọ tààrà bẹ́ẹ̀ sì ni kì í sí ìdíwọ́ rárá fún ènìyàn láti tètè mọ ìtumọ̀ rẹ̀. Àsọyé àti àgbọ́yé ni ó jẹ èdè ojoojúmọ́ lógún àti pé àsọyé kò lè wáyé nínú rẹ̀ láìjẹ́ pé ìlò èdè wà ní ìbámu pẹ̀lú òfin gírámà gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

i. Ọmọ tí àwa kọ ẹnu ìfẹ́ sí tí kò gbà tẹ́lẹ̀ ti wá 'gbà' báyìí!

Nínú ìsọ òkè yìí, a wòye pé kò sí ọ̀rọ̀ kankan tí ó rújú, tó tún ta ko òfin gírámà rárá àti pé ohun gbogbo wà létòlétò bẹ́ẹ̀ sì ni àgbóyé kò níra. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ nínú èdè ewì tí ó jẹ́ pé ìṣọwọ́lo èdè rẹ̀ kò lọ tààrà nítorí pé ijinle ede tí a tún dárà sí ni a fi ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

ii. Ọmọ tí àwa kọ ẹnu ìfẹ́ sí tí kò gbà tẹ́lẹ̀ ti wá 'gbóríwọlé' báyìí!

Ọ̀rọ̀ tí ó dá yàtọ̀ nínú ìsọ òkè yìí ni 'gbóríwọlé' àti pé òun ni àkànlò èdè tuntun tí ó fa ìyàtọ̀ láàrin àpẹẹrẹ (i) ati (ii) nítorí pé èdè ewì ti wà nínú rẹ̀, èyí kò sì jẹ́ kí ìtumọ̀ rẹ̀ lọ tààrà bí ìtumọ̀ ìsọ ojoojúmọ́. Ènìyàn yóò kọ́kọ́ rò pé ẹni tí à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ gbé orí síta láti inú ọkọ̀ tàbí ojú fèrèsé rẹ̀ kí ó tó wá gbé orí ọ̀hún wọlé padà. Irú ìsọ báyìí máa ń dẹ́rìn-ín pa ènìyàn, ó sì ń dánilárayá bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó ta ko òfin gírámà ní ti ìtumọ̀ léréfèé. Ìdí ni pé, kí ènìyàn 'gbà' tàbí 'jẹ́ ò o' kò lè ní ìtumọ̀ 'gbórí wọlé' láìjẹ́ pé onítọ̀hún gbé orí síta nínú ọkọ̀ tàbí lójú fèrèsé ilé tí a wá sọ fún un pé kí ó gbórí wọlé. Irú ìsọ báyìí ti bọ́ sí abẹ́ èdè ewì nípa ìtumọ̀ tí ó yapa sí ìtumọ̀ èdè ojoojúmọ́ àti pé ìlànà àtupalẹ̀ yìi náà ni a lò fún ìtúpalẹ̀ tí a ṣe fún gbogbo àkànlò èdè Yorùbá tuntun tó jẹyọ nínú àpilẹ̀kọ yii.

## Ìṣẹ̀dá Àkànlò Èdè Yorùbá Tuntun

Tí a bá gùn lé ohun tí Bámgbóṣé (1975;205) sọ, a ó ri pé káríayé ni ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun jẹ́ àti pé ó ní ète ìṣẹ̀dá èdè èyí tí a fi ń mọ bí a ṣe ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun kọ̀ọ̀kan. Lára àwọn ètè èdè tí a lò fún ìṣẹ̀dá àkànlò èdè Yorùbá tuntun nìyí:

### Àyálò Ọ̀rọ̀

Gẹ́gẹ́ bí Yule (2007) ṣe sọ, yíyá ọ̀rọ̀ láti inú èdè kan sí èkejì lè wáyé nípa wí pé àwọn tí ó yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè kan wá sínú èdè tiwọn kò ní ọ̀rọ̀ tí ó lè ṣe wẹ́kú pẹ̀lú èdè náà èyí tí ó lè ṣàlàyé kíkún nípa ohun tí wọ́n fẹ́ sọ nínú èdè tiwọn. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, tí ọ̀rọ̀ àyálò bá wọnú èdè kan, ó lè jẹ́ pé àwọn tí ó ṣe àmúlò rẹ̀ kàn lò ó fún ìdárayá ni kì í ṣe pé wọn kò ní ọ̀rọ̀ fún irú ìsọ bẹ́ẹ̀ nínú èdè wọn. Ìwọ̀nyí ni àpẹẹrẹ àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí ó ṣúyọ nípasẹ̀ àyálò ọ̀rọ̀:

| Àkànlò Èdè | Ìṣẹ̀dá wọn | Ìtumọ̀ léréfèé | Ìtumọ̀ Àkànlò Èdè |
|---|---|---|---|
| Kébù lọ | Kébù lọ - àpapọ̀ àyálò ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì (cable) àti Yorùbá (lọ) | Lọ pẹ̀lú wáyà/ wáyà lọ | Tẹná kanlẹ̀/ sáré lọ (wáyà tí ó wà fún títẹ iná mọ́tò ni cable) |
| Ṣádò wọn | Ṣádò + wọn - àpapọ̀ àyálò ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì (shadow) àti ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta (wọn) | Ọ̀rọ̀ àṣẹ láti ọ̀dọ̀ awakọ̀ sí ọmọ ìjẹ̀kà | Wá èrò sínú ọkọ̀/wòó bóyá àwọn èrò yẹn ń lọ |

**Àtẹ 1: Àpẹẹrẹ Àwọn Àkànlò Èdè Yorùbá Tuntun tí ó Ṣúyọ Nípasẹ̀ Àyálò Ọ̀rọ̀**

### Ìsọdorúkọ

Ọ̀kan lára èròjà pàtàkì fún ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun nínú gbogbo èdè àgbáyé ni ìsọdorúkọ jẹ́. Ruwet (1973:173) ṣe àpèjúwe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àpólà orúkọ tí ó jẹ yọ láti ara gbólóhùn tàbí ọ̀nà tí à ń gbà láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ láti ara àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ mìíràn. Bí àpẹẹrẹ: Table 1.2

| Àkànlò Èdè | Ìṣẹ̀dá wọn | Ìtumọ̀ léréfèé | Ìtumọ̀ Àkànlò Èdè |
| --- | --- | --- | --- |
| Ọlọ́ṣẹkọ́ṣẹ | Oní + ọṣẹ + kí + ọṣẹ<br>Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ oní + ọ̀rọ̀ orúkọ + àfòmọ́ ààrin + ọ̀rọ̀ orúkọ | Ẹni tí ó ni ọṣẹ tí kò dára | Olóríburúkú |
| Ẹ̀gúnjẹ | Ẹ + gún + jẹ<br>Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ Ẹ + ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là | Ìṣẹ̀dá èyí jọ ti àgúnmu. Egbò igi tàbí ohun tí a gún jẹ | Rìbá/owó àìtọ́ |

**Àtẹ 2: Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀**

### Síso Ọ̀rọ̀ Pọ̀

Síso ọ̀rọ̀ pọ̀ ni Ògúnbọ̀wálé (1967), Rowland (1969) àti Owólabí (1976) pè ní ṣíṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ nípa àkànpọ̀ ẹyọ ọ̀rọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ èyí tí wọ́n lè dá dúró fúnra wọn láti fún wa ní ìtumọ̀ tí ó yàtọ̀ sí ìtumọ̀ wọn ní ẹyọ kọ̀ọ̀kan. Ìṣẹ̀dá àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí ó fara pẹ́ síso ọ̀rọ̀ pọ̀ máa ń ní ihun ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀-orúkọ báyìí (VB + N) tàbí ($N_1$ + $N_2$). Bí àpẹẹrẹ:

Table 1.3

| Àkànlò Èdè | Ìṣẹ̀dà wọn | Ìtumọ̀ léréfèé | Ìtumọ̀ Àkànlò Èdè |
| --- | --- | --- | --- |
| Gbéṣẹ́ | Gbé + iṣẹ́<br>V + N | Gbé iṣẹ́ tí à ń ṣe | Ṣòwò nàbì/aṣẹ́wó |
| Gbọ́jà | Gbé + ọjà<br>V + N | Gbé ọjà nílẹ̀/rù | Ṣòwò tó lòdì sí òfin |
| Àtíkè ọlà | Àtíkè + ọlà<br>$N_1$ + $N_2$ | Àtíkè tí ó ń sọ ènìyàn dolówó | Òògùn olóró bíi Kokéènì |
| Oṣòdì òkè | Oṣòdì + òkè<br>$N_1$ + $N_2$ | Oṣòdì tí ó wà lókè | Ọyàn ńlá tí ó rẹwà |

**Àtẹ 3: Síso Ọ̀rọ̀ Pọ̀**

## Ìtúpalẹ̀ Àṣàyàn Àkànlò Èdè Yorùbá Tuntun Nínú Orin Tàka-Súfèé

Àkànlò èdè Yorùbá tuntun méjìlá ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a ṣe ìtúpalẹ̀ wọn kí á lè mọ ìtumọ̀ àti ìwúlò wọn gẹ́gẹ́ bí ìpèdè tí a lè lò fún orin kíkọ ati ìdárayá. Àkànlò èdè Yorùbá tuntun mẹ́rin mẹ́rin ni a mú nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan olórin tàka-súfèé tí a yan orin wọn láàyò. Ọ̀pọ̀ nínú àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí ní wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀ tí a ṣe àgbélẹ̀rọ wọn àti àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ti wà tẹ́lẹ̀ nínú èdè ṣùgbọ́n tí a wá gbé ìtumọ̀ mìíràn gun orí wọn.

**'Ẹnu gbẹ': Ọlátúnjí Ọládọ̀tun Àlàdé (Dotman)**

'Ẹnu gbẹ' (Dotman)
Ìgbà 'tẹnu gbẹ', ìgbà ta ò rí nǹkan jẹ 2x
Wọ́n yẹra fún wa ò, wọ́n 'já pa'
Wọ́n yẹra fún wa ò, wọ́n sá lọ
Wọ́n feré ge o, wọ́n gbéra
Wọ́n yẹra fún wa ò, wọ́n 'já pa'

Ọwọ́ epo, a ti mọ̀ wọ́n o, ọwọ̣ epo
Àwọn alábòòsí ọwọ́ epo
Àwọn atẹ́nù yìí ọwọ́ epo
Yéè! Ọwọ́ epo, a ti mọ̀ wọ́n o, ọwọ́ epo
Àwọn aláròpin ọwọ́ epo
Àwọn atẹ́nù yìí ọwọ̣ epo

Wọ́n fi scope wọ́n fi shenk wa
Lórí whatsapp wọ́n tún block wa
A kí wọn, kí wọn wọn ò respond wa
Wọn ò fẹ́ kówó 'lẹ̀, wọn ò fẹ́ sponze wa
Tóri nígbà kan mi ò ní package
Kò sí manager but mò manage
Wọ́n ti gbà pé stori ma change
Wọ́n tún sọ wí pé mé le ra Range
A ra Range a tún ra G wagon
Ẹ ma sanwó ń sìn-ín tẹ bá ma rí wa jọ̀ọ́
Ẹ rò pé a mọ̀ yín, a ò mọ̀ yín
Tẹ bá 'gbémú' bouncer wọ́n ma nà yín
Ṣe bí upcoming ló máa ń di star
Kín ló wá dé tẹ máa ń bú mi nígbà yẹn tí n bá freestyle?
Ṣe bí a kẹ̀ dẹ̀ ti wá blow ń sìn-ín a ti gbé first
Ẹ dẹ̀ kẹ̀ ti wá show ń sìn-ín …

Ṣé bí ẹ ni kí n send account number
Mo send ẹ times without number
A o rí alert dé bi ta ma rówó
Kí wá lẹ wúlò fún kín ni kókó?
Olówó tí ò ṣàánú ọmọ is a tálikà
To bá help èèyàn ìyẹn làlùbárikà
Àtòrì layé horizontal and vertical
Àwọn to allow ló ma rí ẹ bíi màláikà
A ra Range a tún ra G-wagon

Ìgbà tẹ rí wa 'ẹ fọ́' ẹ fẹ́ ma gbọ̀n
Ẹ rò pé a mọ̀ yín, a ò mọ̀ yín
Ẹ ma kówó fún babaláwo kán ma tàn yín
Ṣe bí upcoming ló máa ń di star
Bó pẹ́ bó yá ẹni tó ń fẹsẹ̀ rìn ó ma lo car
Ṣe bí a kẹ̀ dẹ̀ ti wá blow ń sìn-ín a ṣe concert
Ẹ kẹ̀ dẹ̀ sanwó wá show n sin-in …
(Musixmatchsongwriters:olatunjioladotun-Enugbelyrics©)

*(a) 'Ẹnu gbẹ'*

Yàtọ̀ sí pé akọrin tàka-súfèé yìí ṣe àmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun mẹ́rin nínú orin rẹ̀, àkànlò èdè tuntun 'Ẹnú gbẹ' gan-an ni ó fi ṣe àkọlé orin yìí kí ó lè mú àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lọ́kàn, kí ó sì tún jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lọ́nà tí yóò fi pa owó gọbọi wọlé fún un.'Ẹnú gbẹ' nínú orin yìí kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí àkànlò èdè tiwa-n-tiwa nípa ti ìrísí àti ìhun nítorí pé ẹyọ ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tó wà nínú ìsọ yìí kò lè fún wa ní ìtumọ̀ tí ó lọ tààrà àyàfi ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ bíi ti àkànlò èdè tiwa-n-tiwa. Ìtumọ̀ léréfèé tí yóò fún wa ni pé 'ètè wa méjéèjì àti ẹnu wa gbẹ' bóyá nípa pé a ti sọ̀rọ̀ jù tàbí kí àìsàn ibà tàbí ọyẹ́ jẹ́ kí ẹnu wa gbẹ. Àkíyèsí tí a ṣe nípa orin yìí ni pé ìtumọ̀ tó jinlẹ̀ tí àkànlò èdè tuntun inú ìsọ yìí ní ni 'kò sí owó', 'nǹkan le koko fún èniyàn', 'èniyàn kò r'ọ́wọ́ mú' tàbí 'kí èniyàn má rí ṣe'. Èyí ni ó mú Dotman sọ pé 'ìgbà tẹnu gbẹ', 'ìgbà tá ò rí nǹkan jẹ'; èyí túmọ̀ sí pé 'ìgbà tí òun kò tí ì r'ọ́wọ́ mú'. Irú ìyapa ìtumọ̀ báyìí ni kò jẹ́ kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí bá òfin ìsọ ojoojúmọ́ mu ṣùgbọ́n níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé wọ́n wúlò púpọ̀ gẹ́gẹ́ bí àfikún ẹwà èdè àti fún ìdárayá, ìdí nìyí tí wọ́n ṣe di kò-ṣe-é-má-lò fún àwọn èniyàn nínú ìsọ ojoojúmọ́. Ìṣewẹ́kú ìró ọ̀rọ̀ ní ìparí àwọn ìlà kan nínú orin yìí tún jẹ́ àtinúdá ẹwà èdè tí akọrin yìí lò láti dá èniyàn lárayá. Irú àwọn ìró wọ̀nyí ni àwọn Gẹ̀ẹ́sì pè ní 'rhyme'. Àpẹẹrẹ àwọn ìró ọ̀rọ náà ni - rówó, kókó, tálíkà, àlùbáríkà àti màláíkà. Inú èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n sábà tí máa ń lo irú ẹwà èdè báyìí jù ìdí rèé tí a fi lu àwọn ọmọ Yorùbá tí wọn ń fi èdè Yorùbá kọ orin tàka-súfèé èyí tí orísun rẹ̀ jẹ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì lọgọ ẹnu wí pé wọ́n fakọ yọ nípa lílo irú ẹwà èdè báyìí àti fífi àkànlò èdè Yorùbá tuntun gbé orin tàka-súfèé jáde láti fi gbé èdè àti àṣà wọn láruge. Àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí ti di ìpèdè tí tẹrú tọmọ ń gbà bí ẹni gba igbá ọtí lóde-òní. Ó ti di ohun tí àwọn tó ń ṣ'ètò lórí rédíò àti tẹlifísàn ń lò lóòrèkóòrè, kódà wọ́n ti ń lò ó fún ìpolówó ọjà báyíí..

*(b) 'Já pa'*

Ìsọ òkè yìí náà jẹ́ àkànlò èdè Yorùbá tuntun tó jẹ yọ nínú orin Dotman àti pé ó ṣòro láti fún un ní ìtumọ̀ gíríkì tí a bá gùn lé ìtumọ̀ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan ẹ́yọ ọ̀rọ̀ náà ni. Ìtumọ̀ léréfèé tí 'já pa' lè kọ́kọ́ fún wa ni 'kí okùn tí a fi so nǹkan já pátápátá. A tún lè wò ó gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-ìṣe (já) àti ọ̀rọ̀- àpọnlé (pa) tàbí àpólà-ìṣe (já pa) ní

ti ìrísí àti ìhun pẹ̀lú ìtumọ̀ léréfèé ṣùgbọ́n tí a bá rántí pé ọmọ ènìyàn ni Dotman ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ nínú orin yìí, a ó ri pé kò ṣeéṣe kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ já láìjẹ́ pé a fi okùn so ó mọ́ ibì kan tàbí kí ó jẹ́ pé ìjàm̀bá ọkọ̀ orí ilẹ̀, tí òfurufú tàbí ti ojú irin ni ó ṣẹlẹ̀ sí ẹni náà. Ìtumọ̀ àkànlò èdè tí ó jinlẹ̀ tí 'já pa' máa fún wa gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú abala àkọ́kọ́ ìlà orin náà tó sọ pé 'wọ́n yẹra fún wa ò, wọ́n já pa'. Ó tún lè ní ìtumọ̀ 'kí ènìyàn má mọ ènìyàn nígbà ìṣòro. A tún lérò pé láti ara 'àkíyèsí kí á so ohun ọ̀sìn mọ́lẹ̀ kí ó sì já okùn láti sá lọ ni irú ìtumọ̀ tí a gbé sórí àkànlò èdè yìí fi wáyé. Yàtọ̀ sí ìtumọ̀ tí 'já pa' ní nínú orin yìí, lóde-òní, itumo miiran ti a le fun 'já pa' ni 'sá lọ' 'kúrò lọ́nà' 'rìn jìnnà' 'kúrò níwájú mi' àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kò sí èyí tí a kò le lò nínú àwọn ìtumọ̀ tuntun yìí fún 'já pa', èyí wà lọ́wọ́ bí a bá ṣe lò ó àti ọ̀gangan ibi tí a ti lò ó.

*(d) 'Gbé Imú' (gbé 'mú)*

Ìsọ òkè yìí jẹ́ àkànlò èdè Yorùbá tuntun èyí tó jẹ́ pé o wa ninu ọ̀rọ̀ Yorùbá tí a ti mọ̀ tẹ́lẹ̀ àti pé ó wà ní ìbámu pẹ̀lú bí a ṣe ń sọ̀rọ̀ àti kọ ọ̀rọ̀ sílẹ̀ lèdè Yorùbá, síbẹ̀síbẹ̀ ìtumọ̀ léréfèé tí yóò gbé jáde kò lè jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ní ìbámu pẹ̀lú òfin èdè ójoojúmọ́. Ìdí ni pé, kò bójú ayé mu kí ènìyàn gbé imú ara rẹ̀ lọ́wọ́ láìṣe màlúù tàbí ewúrẹ́ tí a pa, tí a wá kó imú náà sínú igbá fún ẹni tó ni imú láti fi ọwọ́ ara rẹ̀ gbé e. Irú àpẹẹrẹ báyìí ni ó ṣokùnfà tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ tí a lò fún ìtúpalẹ̀. Fún ìdí èyí, nínú iṣẹ́-ọnà tàbí orin báyìí ni a ti lè lo irú ìsọ tí ó tako òfin gírámà àti pé títako òfin gírámà nírú ọ̀nà báyìí jẹ́ ohun tí oníṣẹ́-ọnà mọ̀-ọ́n-mọ̀ fi àtinúdá rẹ̀ ṣe bóyá fún ìbánisọ̀rọ̀ lọ́nà tó jinlẹ̀ tàbí fún ìdárayá. Ìtumọ̀ tí 'gbémú' ní tí ó jinlẹ̀ nínú orin yìí ni 'kí ènìyàn máa kùn', 'kí ènìyàn fi hàn pé ohun tó ṣẹlẹ̀ kò tẹ́ òun lọ́rùn tàbí 'kí ènìyàn má gbà fún Ọlọ́run'. Kò dájú pé a lè rí ọmọ Yorùba kan tí èdè Yorùbá yé dáadáa tí yóò sọ pé òun kò mọ ìtumọ̀ ìsọ yìí lòde-òní àyàfi tí ó bá jẹyọ nínú ìsọ mìíràn tí ó yàtọ̀ sí bí a ṣe lò ó nínú orin yìí; ìdí ni pé ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sì í ọ̀gangan ibi tí kì í tí jẹ yọ.

*(e) 'Ẹ fọ́*

Nínú iṣẹ́ ọnà bí irú orin báyìí náà ni a ti lè kọ́kọ́ rí irú àkànlò-èdè báyìí nítorí pé ìtumọ̀ tí kò lòdì sí òfin èdè ojoojúmọ́ kò lè wáyé níbi tí a bá ti lo ọ̀rọ̀-ìṣe 'fọ́' nínú gbólóhùn 'ẹ fọ̀' fún ènìyàn láìṣe igbá. Ìdi ni pé ènìyàn kì í ṣe ìgò, àwo tàbí ẹyin tí ó lè fọ́ tí ó bá jábọ́ láti òkè. Ṣùgbọ́n irú ìsọ yìí lè jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà nígbà tí a bá rántí pé wíwo ẹyọ ọ̀rọ̀ inú àkànlò èdè fún ìtumọ̀ kò lè fún wa ní ìtumọ̀ tí ó jinlẹ̀. Tíọ́rì tí a lò fún ìtúpalẹ̀ nìkan náà ni ó lè ṣe irú àlàyé báyìí nítorí pé ó fi àáyè gba lílo irú ìsọ báyìí nínú iṣẹ́ ọnà àti pé níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn ti ń lo ìsọ yìí ní oríṣìíríṣìí ọ̀nà láwùjọ fún ìgbà pípẹ́, dandan ni kí ó ṣe kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ wọ inú èdè ojoojúmọ́ wa. Àwọn ọ̀dọ́ fẹ́ràn láti máa lo irú àkànlò èdè tuntun tí ó lè dẹ́rìn-ín pa wọ́n tàbí tí ó lè mú kí wọ́n túraká báyìí nítorí pé ó rọrùn fún wọn láti sọ àti láti gbọ́ ju ọ̀rọ̀ ṣákálá lọ. Èyí gan-an ni yóò jẹ́ kí ó ṣòro fún èdè Yorùbá láti kógbá sílé láwùjọ àwọn èdè tí ó kù nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́

tí kò gbọ́ Yorùbá rárá àti àwọn tí kò lè sọ ọ́ dáadáa ti ń tipasẹ̀ ìṣàmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú irú orin báyìí gbọ́ àti kọ́ èdè Yorùbá. Ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ tí 'ẹ fọ́' ní ni kí 'ẹ̀rù ba ènìyàn' 'kí jìnnìjìnnì dé bá ènìyàn' 'kí ènìyàn máa gbọ̀n', 'kí ẹnu ya èèyàn', 'kí́ jẹbẹtẹ gbọ́mọ lé èèyàn lọ́wọ́' pàápàá jùlọ, nígbà tí a bá rí ẹni tó yẹ kí á ṣoore fún nígbà ìṣòro ṣùgbọ́n tí a kò ṣe é nítorí pé a fi ojú rénà irú ẹni bẹ́ẹ̀ ṣùgbọ́n tí a wá rí irú ẹni bẹ́ẹ̀ ti nǹkan ti dára fún un ju tiwa lọ, ẹ̀rù ní láti bà wá, a ní láti 'fọ́'.

**As E Dey Go (Naira Marley)**

Marlians!
Yó-yò Rexxie pon this one!
Ṣé ẹ ti jẹ̀bà yó ni?
Ẹ ò ṣe ní lè 'gbé bọ́dì" (gbé body) oh
Ṣé ẹ ti jẹ sẹ̀mó yó ni? Ṣo ò ní le…
Ládùgbó mi (ládùgbó mi)
Tí ǹ tì ì yo (tí ǹ tí ì yo)
Tí ǹ tí ì jẹun (tí ǹ tí ì jẹun)
Tí ǹ tí ì 'pa-in' (tí ǹ tí ì pa-in)
Ó wá ń lọ 'húgẹ̀' (ó wá ń lọ húgẹ̀)
Ó wá ń lọ 'gbégè' (ó wá ń lọ gbé 'gẹ̀)
Ah, stop ṣe bẹ́ẹ̀ (stop ṣe bẹ́ẹ̀) ,…
Ó mu'gbó, mu'gbó, mu'gbó (mu'gbó)
Kò r'óunjẹ kò lè sọ̀rọ̀ (ò lè sọ̀rọ̀)
Gàrí à mu kù, ge-ge-gele
Ge-ge o de'le
Má 'f'aṣọ lèmọ́mù ya', ké ké ké, ké-ké
Ẹ má 'f'aṣọ Ààfà ya', kí ló, kí ló dé?
Kí ló tún pé ó dé?
Torí pé a n'ówó nílé …

*(a) Gbé bọ́dì (body)*

Àkànlò èdè Yorùbá tuntun 'gbé bọ́dì' jẹ́ àmúlùmálà èdè Yorùbá (gbé) àti èdè Gẹ̀ẹ́sì 'body' (bọ́dì) èyí tí ìtumọ̀ léréfèé rẹ̀ jẹ́ 'gbé ara nílẹ̀' tí ènìyàn bá jẹ́ ẹni tó sanra. Àmúlùmálà èdè Gẹ̀ẹ́sì àti ede Yorùbá ni àwọn ọmọ Yorùbá tí ó ń kọrin tàka-súfèé sábà máa ń lò jù láti ṣe àgbékalẹ̀ orin won; nígbà mìíràn, wọ́n lè lo Píjìnnì pẹ̀lú rẹ̀ nítorí pé àbájáde àpapọ̀ àwọn ẹ̀yà èdè mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí lè pa ènìyàn lẹ́rìn-ín tàbí kí ó dáni lárayá. Ìdí nìyí tí àwọn ọ̀dọ́ fi gbádùn láti máa gbọ́ irú orin tó ní àmúlùmálà èdè nínú báyìí. Àtinúdá àwọn ọ̀kọrin yìí ni èdè Yorùbá ti wọ́n mú wọ inú orin tàka-súfèé èyí tí orísun rẹ̀ jẹ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Atínúdá yìí gan an ni ó fa àmúlùmálà èdè inú orin tàka-súfèé èyí tí ó yapa sí òfin èdè ojoojúmọ́. Òfin èdè fí àyè gba àyálò èdè ṣùgbọ́n kò

fi àyè gba irú àmúlùmọ́là báyìí nínú èdè ojoojúmọ́ àyàfi nínú iṣẹ́-ona. Ìtumọ̀ 'gbé bọ́dì' nínú orin yìí ni 'kí àwọn tí ó ń gbọ́ orin náà jó kárakára'nítorí pé a lérò pé ọ̀kọrin yìí ṣe àkíyèsí pé wọn kò jó dáadáa. Ìdí nìyí tí ó fi sọ pé 'ṣe ẹ ti jẹ̀bà yo ni tí ẹ è ṣe lè gbé bọ́dì'. Àkànlò èdè tuntun 'gbé bọ́dì' yìí ti di ohun tí tọmọdé-tàgbà mọ ìtumọ̀ rẹ̀ nítorí oríṣìí ọ̀nà ni wọn ń gbà láti lò ó. Nígbà mìíràn, ó lè ní ìtumọ̀ kí ènìyàn 'lo ọpọlọ rẹ̀' tàbí kí ó 'fi ọgbọ́n orí rẹ̀ ṣe nǹkan'.

### *(b) Faṣọ Lèmọ́mù ya*

Àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí jẹ́ irú àkànlò èdè Yorùbá tó ní ìtumọ̀ tí ó jinlẹ̀, tí ó sì tún wà fún ìbánisọ̀rọ̀ àti ìdárayá fún àwọn tí òye lílo àkànlò èdè tètè máa ń yé. Ìtumọ̀ léréfèé ìsọ yìí ni 'kí ènìyàn fa aṣọ ya mọ́ olórí ẹ̀sìn (Lèmọ́mù) lára ṣùgbọ́n níbi tí Naira Marley ti ń kọrin yìí kò sí olórí ẹ̀sìn kankan níbẹ̀. A lérò pé ọ̀kọrin yìí ń fi orin ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn ènìyàn kan tí wọ́n ń hùwà ìgbéraga èyí tí kò nífẹ̀ẹ́ sí ni ó ṣe lo ìpèdè yìí. Kò fi bẹ́ẹ̀ sí ìyàtọ̀ kankan nínú 'faṣọ lèmọ́mù ya' àti 'faṣo Ààfáà ya', ọ̀kọrin kan lo méjéèjì gẹ́gẹ́ bí àwítúnwí tàbí ìtẹnumọ́ ni. Ohun tí 'faṣọ Lèmọ́mù ya' túmọ̀ sí ni pé, 'kí wọ́n má wá ìbínú òun', kí wọ́n má fọwọ́ fa ohun tí ipá wọn kò ní ká' tàbí 'kí wọ́n má fa ìjọ̀ngbọ̀n lẹ́sẹ̀'. Ìtumọ̀ yìi yóò ti yé àwọn tí ó ní òye irú ẹni tí Lèmọ́mù jẹ́ nínú ẹ̀sìn Mùsùlùmí gẹ́gẹ́ bí ẹni ọ̀wọ̀ tí ó mọ àlùkùráánì dé bi pé tí ó bá jẹ́ onínú fùfù ènìyàn ni, ó lè lò ó láti fi jẹ ènìyàn níyà tí irú ẹni bẹ́ẹ̀ bá kọjá àyè rẹ̀ lọ́dọ̀ rẹ̀. Kò sí bí ẹ̀rín kò ṣe ní pa ènìyàn tí ó gbọ́ irú ìpèdè báyìí nítorí pé èèyàn yóò fẹ́ láti bèèrè wí pé kí ló kan lèmọ́mù nínú ọ̀rọ̀ báyìí? Àkànlò èdè tuntun yìí fara pẹ́ àkànlò èdè tiwa-n-tiwa 'má forí jálé agbọ́n' nípa ti ìtumọ̀. Ìtumọ̀ 'kí ènìyàn má fi ọwọ́ ara rẹ̀ fa wàhálà ni 'faṣọ lèmọ́mù ya' àti 'forí jálé agbọ́n ní.

### *(d) Pa-in*

Àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí jẹ́ àkànlò èdè tuntun tí ó ní ìrísí fìrósínròòjẹ. Irú àkànlò èdè báyìí jẹ́ èyí tó jẹ́ pé bí ìró wọn bá ṣe dún ni ó ń jẹ́ kí á mọ ìtumọ̀ wọn. Ọ̀rọ̀ onísílébù méjì ni 'pa-in' (pa-in), ìró ohun àárín méjì (re/re) ni ó ní pẹ̀lú. Ìtumọ̀ àkànlò tí ìró yìí gbé jáde ni 'kí nǹkan kọ iṣẹ́', 'ṣíwọ́ iṣẹ́' tàbí 'kú' bí ìgbà tí ẹ̀rọ kan tó ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ déédé gbé ìró 'pa-in' jáde kó sì ṣíwọ́ iṣẹ́. Ó lè jẹ́ ènìyàn kan tí ó ń ṣe àárẹ̀ tàbí tó wà lójú ikú, tí ó wá déédé mí kanlẹ̀ 'pa-in' tàbí kí ó 'pa eyín pọ̀' 'pa-in' kí ó sì gbé ẹ̀mí mì. Ohun tí Naira Marley ń fi 'pa-in' ṣàlàyé nínú orin rẹ̀ ni pé 'tí òun kò tíì kú' (pa-in)', kò sí ẹni tí ó lè máa fọwọ́ lalẹ̀ foun ní sàkání òun. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́ tó jẹ́ ọmọ Yorùbá ni ó máa ń lo ìpèdè yìí lóde-òní láti pẹ́ ọ̀rọ̀ sọ tí wọn kò bá fẹ́ fi gbogbo ẹnu sọ pé ènìyàn kú. Pípẹ́ ọ̀rọ̀ sọ yìí gan-an ni kókó iṣẹ́ tí a máa ń fi àkànlò èdè ṣe.

### *(e) Gbégè̩/húgè̩*

'Gbégẹ̀' (gbé igẹ̀) tàbí húgẹ̀ (hú igẹ̀) náà jẹ́ àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí ìtumọ̀ rẹ̀ jinlẹ̀ tí ó sì yapa sí ìtumọ̀ tí a lè rí nínú èdè ojoojúmọ́. Ìtumọ̀ tí ìsọ yìí

lè kọ́kọ́ ní sí wa ni ‘kí èniyàn fi ọwọ́ gbé igẹ̀ nǹkan’ tàbí ‘kí ó ru àyà síta nítorí pé òkè àyà èniyàn ni ẹ̀yà ara tó ń jẹ́ igẹ̀ wà. Ìtumọ̀ àkànlò tí ‘gbé ‘gẹ̀’ tàbí ‘hú ‘gẹ̀’ ní sí àwọn èniyàn lóde òní kò ṣàjèjì sí wọn rárá nítorí pé oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn èniyàn tí ń bá ìsọ yìí pàdé nínú èdè ójoojúmọ́. Ó sì ti di bárakú lọ́nà tó jẹ́ pé yóò ṣòro fún èniyàn láti ri ìyapa ìtumọ̀ rẹ̀ sí ti èdè ojoojúmọ́. Ìtumọ̀ àkànlò tí àkànlò èdè tuntun yìí ní ní ọ̀gangan ibi tí a ti lò ó nínú orin yìí ni ‘kí èniyàn gbéraga’ tàbí ‘ṣe àfojúdi sí èniyàn’, ‘jọ ara ẹni lójú’ tàbí ‘kí ó sọ pé kò sí irú òun’.

**Ó Ń Gbá Lára Mi – (Oritse Fẹ́mi)**

Ṣẹ ti jẹ, ṣẹ ti jẹ?
Ṣẹ ti jẹ, ṣe ti jẹ?
Ṣẹ ti jẹ, ṣe ti jẹ?
Ṣẹ ti jẹun?
Mo ti mu, mo ti mu
Mo ti mu, mo ti mu
Mo ti mu, mo ti mu
Mo ti yó
Everything just dey go sẹ̀rẹ̀rẹ̀ (sẹ̀rẹ̀rẹ̀)
Everything dey dance ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ (ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀)
A má jayé mọ́jú kẹlẹlẹ (ẹlẹlẹ)
Ẹ̀yin tèmi ẹ maa múra á lẹ̀
Ọ̀dọ́mọdé ẹ jíjó mi
Àgbàlagbà ẹ jíjó mi
Ọmọ’gboro jíjó mi
Ká jọ ma ‘kojẹ bí indomie’
Bo ṣe ń ṣe yẹn ni ko máa ṣe (ko máa ṣe)
Bo ṣe ń gbe yẹn ni ko máa gbe (ko máa gbe)
‘Ṣó ń gbá lára ẹ’
‘Ó ń dún lára mi’
Ezego lára mi …
All these people want to cause ‘gòòbe’
Wọ́n dẹ̀ mọ̀ páwa la lòde
Ta ló ‘fa wèrè lọ́yàn’? (hmmm hmmm)
Ta ló ‘fa wèrè lọ́yàn’? (hmmmm hmmm)
Ṣé wọ lo fa wèrè lọ́yàn? (Ehh, ehh)
Ẹ ti lọ fa wèrè lọ́yàn (ehnn, ehn)
‘Ó ń gbá lára ẹ’
Ó ń dún lára mi …
(musixmatchsonywriters:ongbalara mi lyrics©)

*(a) Kó jẹ bíi Indomie*

Ìrísí àti ìhun àfiwé ni àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí ní àti pé àfiwé tààrà ni irú àfiwé yìí, ó sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà bí a ṣé ń sọ̀rọ̀ lójoojúmọ́ ṣùgbọ́n ó yapa ní ti ìtumọ̀; ìtumọ̀ léréfèé tí 'kó jẹ bíi indomie' yóò fún wa ni 'jíjẹ oúnjẹ tí a fẹ́ràn wàdùwàdù ṣùgbọ́n tí a bá wo bí a ṣe lo ìsọ yìí nínú orin Oritse Fẹ́mi, a ó ri pé ó jọ èdè ewì nítorí pé ijó tàbí orin kíkọ kì í ṣe oúnjẹ tí ènìyàn ń jẹ. Iṣẹ́-ọnà ni akọrin tàka-súfèé yìí fi ṣe. Ó kàn lò ó gẹ́gẹ́ bí àfiwé tààrà ni nípa fífi bí àwọn ọ̀dọ́ àti ọmọdé ayé òde-òní ṣe fẹ́ràn láti máa jẹ oúnjẹ ìgbàlọ́dé kan tí ó ń jẹ́ indomie wé bí wọ́n ṣe máa fẹ́ràn orin àti ijó tirẹ̀ ni. Ìtumọ̀ àkànlò tí ìsọ yìí ní ni pé 'kí wọ́n fẹ́ràn orin òun' 'kí wọ́n gba ti orin àti ijó òun' 'kí wọ́n jó sí orin àti ìlù òun kárakára ati 'kí wọ́n rọ́ tìkẹ́tìkẹ́ lọ ra àwo orin òun. Àkànlò èdè yìí gan-an ni àwọn tí wọ́n ń ta oríṣìírísìí ọjà sáábà máa ń lò fún ìpolówó ọjà wọn jù lọ lóde òní.

*(b) Ṣó ń gbá lára ẹ (mi)*

Ìṣàmúlò irú àkànlò èdè Yorùbá tuntun yìí gba ọgbọ́n àtinúdá tí ó jinlẹ̀ àti pé àwọn ọ̀dọ́ tó mọ tìfun-tẹ̀dọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí Oritse Fẹ́mi nàà ló lè ṣe àmúlò irú ìsọ yìí láti dá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lárayá. Abájọ tí ó fi lò ó gẹ́gẹ́ bí àkọlé orin rẹ̀ lọ́nà tí ìsọ nàà fi pàkíyèsí ara rẹ̀ nítorí pé kì í ṣe irú ọ̀rọ̀ tàbí ìpèdè tí a máa ń bá pàdé nínú ìsọ ojoojúmọ́ sáájú àsìkò yìí gẹ́gẹ́ bí tíọ́rì tí a lò fún àpilẹ̀kọ yìí ṣe ṣàlàyé. Ọ̀rọ̀-ìṣe àti àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ inú ìsọ yìí kò lè dá fún wa ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ ní ẹyọ ọ̀rọ̀ sí ẹyọ ọrọ nítorí pé epo tàbí òróro ni a máa ń gbá lórí iná gẹ́gẹ́ bí ohun tẹnu ń jẹ; ènìyàn kì í ṣe iná tí a lè gbá epo lórí rẹ̀. Iṣẹ́-ọnà ló fi ìsọ yìí ṣe nínú orin rẹ̀ láti jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ mọ̀ wí pé 'orin àti ijó ń gùn ún tàbí pé ó ń gbé wùkẹ̀wùkẹ̀ lọ́kàn rẹ̀. Ní kúkúrú àti ní ìbámu pẹ̀lú bí a ṣe lo ìsọ yìí nínú orin, ìtumọ̀ 'ó ń gbá lára mi' ni pé 'orin ń gùn mí', 'orin wà lára mi', 'orin ń gbé mi lọ́kàn. Lóde-òní, a lè lo 'ọ ń gbá lára mi' fún ohunkóhun tí a bá mọ̀-ọ́n-ṣe bí ìwé kíkà, bọ́ọ̀lù gbígbá, ọ̀rọ̀ sísọ, ọkọ̀ wíwà, ijó jíjó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kí á wá sọ pé ohun nàà 'ń gbá lára wa'.

*(d) 'Gòòbe'*

Fìrósínròòjẹ ni ìṣẹ̀dá àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí a pè ní 'gòòbe' yìí. Èyí ni ọ̀rọ̀ tó jẹ́ pé bí ó ṣe dún létí wa ni a fi mọ ìtumọ̀ tí ó ní. Yàtọ̀ sí pé fìrósínròòjẹ ni a fi ṣẹ̀dá rẹ̀, ó tún jẹ́ ẹyọ ọ̀rọ̀ tí orísun rẹ̀ wá láti inú èdè Hausa èyí tí ìtumọ̀ rẹ̀ jẹ́ 'ọ̀la' tàbí 'ọjọ́ ọ̀la' ṣùgbọ́n tí a gbé ìtumọ̀ tuntun mìíràn gun orí rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe lò ó nínú orin yìí àti nínú ohun mìíràn tí àwọn ènìyàn tún ń lò ó fún, ìtumọ̀ 'wàhálà', 'ìjàngbọ̀n', 'làásìgbò' tàbí 'họ́wùhọ́wù' ni 'gòòbe ní. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé àwọn ọ̀dọ́ àti àwọn ènìyàn mìíràn tó ń ṣàmúlò èdè Yorùbá fẹ́ràn irú àwọn ìsọ báyìí àti pé ìṣàmúlò wọn nínú irú orin tàka-súfèé báyìí ń máa ń jẹ́ kí wọ́n túraká.

*(e) Fa wèrè lọ́yàn*

Ìrísí àti ìhun àkànlò èdè tiwa-n-tiwa ni 'fa wèrè lọ́yàn' ní àti pé ìṣẹ̀dá rẹ̀ gan-an kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ti àkànlò èdè tiwa-n-tiwa èyí tó jẹ́ pé 'mẹ́táfọ̀' ní a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn. 'Fa wèrè lọ́yàn' wà ní ìbámu pẹ̀lú bí a ṣe ń sọ ọ̀rọ̀ nínú èdè ojoojúmọ́ ṣùgbọ́n ìtumọ̀ àkànlò èdè tí ọ̀rọ̀ yìí fún wa ni ó jẹ́ kí ó rú òfin èdè ojoojúmọ́ àti pé ìtumọ̀ yìí gan an ni ó sọ ọ́ di iṣẹ́-ọnà. Ènìyàn lè 'fa wèrè lọ́yàn' ṣùgbọ́n kí ni ẹni tó bá ṣe bẹ́ẹ̀ ń wá? Dájúdájú ẹni náà ń wá 'wàhálà', 'ìyọnu', 'ìjàngbọ̀n', àti 'ìpalára'. Bí ìgbà tí ajá bá wọlé tọ ẹkùn lọ ni àti pé ohunkohun tó burú jáì ni ẹni tó ní àìsàn ọpọlọ lè ṣe fún ẹnikẹ́ni tó bá gbìyànjú láti 'fa wèrè lọ́yàn. Kì í kúkú ṣe pé ẹnì kan ń gbìyànjú láti fa wèrè lọ́yàn, lílo irú àkànlò èdè báyìí wà fún pípẹ́ ọ̀rọ̀ sọ tàbí kí á fi ọ̀rọ̀ pa òwe fún ènìyàn. Àwọn tó bá gbọ́ Yorùbá dáadáa ni òye lílo àkànlò èdè wà fún ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ yàtọ̀ sí òde-òní tí àwọn ọ̀dọ̀ gbádùn láti máa lo àkànlò èdè tuntun bí i ti 'fa wèrè lọ́yàn fún ìdárayá. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn ọ̀dọ́ ń ṣe àwòkọ́ṣe àṣà àwọn òyìnbó tí kò fi àyè gba pípẹ́ ọ̀rọ̀ sọ fún àwọn ibi ìpamọ́ ọkùnrin àti obìnrin lórí ẹ̀rọ ayélujára. Ìtumọ̀ àkànlò tí ọ̀rọ̀ yìí ní ní ọ̀gangan ibi tí a ti lò ó nínú orin ni pé 'ta ló ń wá ìyọnu'? Ta ló ṣetán ikú? Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ìrísí, ìhun àti ìtumọ̀ àkànlò èdè tiwa-n-tiwa tí a mọ̀ sí 'forí jálé agbọ́n' 'kán róro nírù' àti 'finá sórí òrùlé sùn'.

## Àbájáde Ìtúpalẹ̀

Kókó tí a rí fàyọ nípasẹ̀ ìtúpalẹ̀ tí a ṣe nínú àpilẹ̀kọ yìí ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè Gẹ̀ẹ́sì ni orísun èdè tí a fi ń kọ orin tàka-súfèé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ wá; àpilẹ̀kọ yìí ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó ṣeé ṣe láti fi èdè Yorùbá kọ orin tàka-súfèé nípa ṣíṣe àmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun lọ́nà tí yóò wuyì, tí yóò sì jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ju èyí tí a fi èdè Gẹ̀ẹ́sì gan an kọ lọ. Èyí já sí pé kò sí ohun tí a lo èdè Gẹ̀ẹ́sì fún nínú orin tàbí nǹkan mìíràn lábẹ́ ọ̀run tí a kò lè ṣe jù bẹ́ẹ̀ lọ pẹ̀lú èdè Yorùbá.

Ẹ̀rí tó dájú tún fi hàn kedere nínú ìtúpalẹ̀ wa wí pé ṣíṣe àmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun rọrùn púpọ̀ fún ìpanilẹ́rìnrín àti ìdánilárayá nínú orin tàka-súfèé. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ Yorùbá tí kò gbọ́ èdè Yorùbá dáadáa tẹ́lẹ̀ rí àti àwọn elédè mìíràn ni wọ́n ń tipasẹ̀ orin tàka-súfèé èyí tí a lo èdè Yorùbá nínú rẹ̀ gbọ́ èdè Yorùbá.

Àpilẹ̀kọ yìí tún jẹ́ kí á mọ̀ pé àkànlò èdè Yorùbá tuntun gan-an ni ó mú àkànlò èdè Yorùbá yàtọ̀ sí èdè àfidáṣà (slang) tó jẹ́ pé wọ́n kò ní ètè èdè tí a fi ṣẹ̀dá wọn àti pé àwọn tí ó ń ṣe àmúlò wọn máa ń lò wọ́n láàrin ara wọn gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ tàbí ọ̀wọ́ kan fún ìdánimọ̀ lásán ni kì í pẹ́ pòórá nílẹ̀ bí isó lẹ́yìn ìgbà díẹ̀. Kò dàbí àkànlò èdè Yorùbá tuntun tó jẹ́ pé wọ́n máa ń wà ní àwùjọ fún ìgbà pípẹ́. Lóòótọ́ kì í ṣe ìṣẹ̀dá àkànlò èdè tuntun ni ó jẹ wá lógún jù nínú àpilẹ̀kọ yìí ṣùgbọ́n a jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé ìṣẹ̀dá àkànlò èdè Yorùbá tuntun sábà máa ń jẹ́

èyí tí a fi mẹ́táfọ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ nínú èyí tí a ti rí ìsọdorúkọ, àyálò ọ̀rọ̀, fìrósínròójẹ, àfiwé tààrà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Nínú àpilẹ̀kọ yìí náà ni a ti mọ̀ pé lóòótọ́, àkànlò èdè Yorùbá tuntun dàbí èdè ewì gege bi àlàyé tí a ṣe nínú tíọ́rì ìṣàmúlò wa ṣùgbọ́n nípasẹ̀ lílò wọ́n nígbà gbogbo nínú oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ àti bí wọ́n ṣe ń bùkún ẹwà èdè Yorùbá ní ó sọ wọ́n dí ìpèdè bárakú tó ṣe kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ yí wọnú èdè ojoojúmọ́.

## Ìkádìí

A ti ná ìgbárá, a sì ti ná ìgboro, a ti rí i pé àpilẹ̀kọ yìí ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àpẹẹrẹ tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nípa ohun tí àkànlò èdè Yorùbá tuntun jẹ́. Ẹ̀rí tó fẹsẹ̀ múlẹ̀ tún fi dá wa lójú pé iṣẹ́ ti wà nílẹ̀ lórí ìṣàmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun fún àgbékalẹ̀ oríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀tun nínú ètò ìṣèlú, ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀, ìgbòkègbodò ọkọ̀, fíìmù àgbéléwò, ìṣètò lórí rédíò, ìpolówó ọjà, ìròyìn eré bọ́ọ̀lù ṣíṣe àti ìtàkurọ̀sọ ní gbàgede ìwòran eré bọ́ọ̀lù. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé òtítọ́ ni iṣẹ́ ti pọ̀ lórí àkànlò èdè Yorùbá tuntun nínú gbogbo ọ̀nà tí a mẹ́nu bà síwájú yìí, a jẹ́ pé akanlo ede Yoruba tuntun ti di òdú tí kì í sàìmọ̀ fún olóko àti pé èyi gan-an ni ó fi wá lọ́kàn balẹ̀ pé èdè Yorùbá kò lè sí lára àwọn èdè tí ó lè parun lọ́jọ́ iwájú. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé nípasẹ̀ ìṣàmúlò àkànlò èdè Yorùbá tuntun, èdè Yorùbá tún ti ní ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ mìíràn tí a fi ń lo èdè èyí tí àwọn èdè mìíràn kò ní. Kì í ṣe gbogbo èdè ni a ti lè rí ibi tí èdè iṣẹ́-ọnà ti ń yíra padà di èdè ojoojúmọ́ bíi ti àkànlò èdè Yorùbá tuntun tí àpilẹ̀kọ yìí dá lé lórí. Ìmọ̀ràn tí àpilẹ̀kọ yìí ń gba gbogbo ọmọ Yorùbá pátápátá ni pé kí á mú èdè Yorùbá ní ọ̀kúnkúndùn kí iná èdè náà má ba à jó rẹ̀yìn, kí wọ gbìyànjú láti máa ṣe àmúlò èdè Yorùbá ní ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ àti ní oríṣìí àwọn ọ̀gangan ibi tí iṣẹ́ kò tí ì dé. Ìdánilójú wà pé èdè àti àṣà wa ti tó láti gbé wa dé ilẹ̀ ìlérí níbi tí àwọn èdè orílẹ̀-èdè alágbára ayé bí i Amẹ́ríkà, Faransé ati Lárúbáwá wà lónìí.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Akanmu, Samuel. ‘’New Idioms and idiomatic Expressions in Yoruba Literary and Routine Communication’’. Unpublished doctoral dissertation, University of Ibadan, Ibadan (Nigeria), 2014.

Akanmu, D. “Language and Culture among the Yoruba: A study of Argot, Cant, Jargons and Slang as Forerunners of New Idioms and Idiomatic Expresssion in the 21st Century”, *Innovation and Applied Studies* 3.3 (2015): 669-676

Akanmu, D. “Cummicative and Stylistic Utilisation of New Yoruba Idioms Among Student of Higher Institutions”. *Argotica*, 1.5 (2016): 45-56.

Akanmu, D. “New Yorùbá Idioms and Idiomatic Expressions: A New Mode of Expression in Political Arena”. *Dialectologia*, 19. (2017): 23-40.

Akanmu, D. (2018) "The Phenomenon of New Yorùbá Idioms and Idiomatic Expressions in Football Matches: Communicative and Stylistic Approach". *Logos and Littera*, 5.1, (2018): 104-120.

Akanmu, D. ''Communicative and Stylistic Potential of New Yorùbá Idioms and Idiomatic Expressions on the Label of Alcoholic Drinks". *Arbitrer*, 2.6, (2019): 92-98

Akanmu, D. "Àkànlò Èdè Yorùbá Tuntun Gẹ́gẹ́ bí Èdè Ìpolówó Ọjà ara Ìgò Ọtí Líle tí ó ní Àgbo nínú". *Ọ̀páḿbàtà*, 8. (2020): 99-111.

Alaba, O. "Ọgbọ́n Ìtọpinpin Ewì Yorùbá". *Yorùbá Gbòde*, 1.8, (1992):

Adedeji, S. (2004) "Nigerian Gospel Music: A Study of Its Style". Unpublished doctoral dissertation, University of Ìbàdàn, Ibadan (Nigeria), 2004.

Adẹgbite, A. (1994) "The Influence of Islam on Yorùbá Music", *Oríta Ì bàdàn*, 1.2, (1994):

Agbaje, Joel "A Literary Study of the Folksongs of the È kìtì People of Nigeria". Unpublished doctoral dissertation, University of Ìlọrin, (Nigeria), 1995.

Ajibade, A.O. "New Wine in Old Cups: Post Colonial Performance of Christian Music in Yorùbá land". *Studies in World Christianity*. 13. (2011):

Babalọla, Ayo "The Growth of the Yorùbá Language: Problems Encountered and Solutions". Essayed Staff Seminar Papers and Subsequent Discussions. Ìlọrin (Nigeria), Chridamel Press, 1972.

Bámgboṣe, A. "Relative Clauses and Nominalised Sentences in Yorùbá". In *Proceedings of Sixth Conference on African Linguistics*, OSU WPL 20, ed. R. K. Herbert, 202-209 (Nigeria): 1975.

Bámgboṣe, A. "Corpus Planning in Yorùbá Technicians of the Sacred". *Research in Yorùbá Language and Literature*, (1992): 1-13; UNESCO.

Daramọla, A. "The Musical Concept of the Alásàlátù in Yorùbá Islamic Music", Unpublished doctoral dissertation, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀, Osun (Nigeria), 2008.

Elugbe, B. (2012), "Nigerian Pidgin: Problems and Prospects". In *New Englishes: A West African Perspectives*, ed. A. Bamgbose et al, Ìbàdàn (nigeria): Mosuro, 2012.

Kukọyi, E. "Gospel Music", *Praise the Lord News*, 2.8, (1995): 6.

Keyes, Corlins. *Rap Music and Street Consciousness*. Urbana and Chicago: University of Illinois Press, 2009.

Lamidi, M.T. "The Scopal Authority of Heads in Yorùbá-English Code – Switching" *Nordic*, 13.1, (2011): 76-94.

Mukarovsky, J. (1970) "Standard and Poetic Language" in *Linguistic and Literary Style*, ed. D.C. Freeman, Massachusett (USA): H.R.W. 1970.

Ogunbọwale, J. *Essential of the Yorùbá Language*: Ìbàdàn University Press, 1967.

Ọlatẹju, M.O.A "The Phenomenon of New Idioms In Yorùbá Literary and Routine Communication'' In *Gentivities, Fiction, Language and Song*, ed. T. Fálọlá, and Ann Geneova, 273-287. 2005.

Ọlatẹju, M.O.A "Jẹ̀dí Ò Makọ̀wé",: A Socio Linguistic Analysis of the Language Style of the Yorùbá Herbal Medicine Practitioners". *Proceedings Linguistics*, (ACAL), (2008):

Ọlatẹju, M.O.A "Current Issues and Trends in African Verbal Stylistics: the Yorùbá Example", in *Style in African Literature* 12, ed. Makokha, J.K.S Obiero, and W. Pavlov, 59-70. (Amsterdam): New York, Radopi, 2012.

Ọlatẹju, Moses, "Language and Style (-Listics) in Literary and Routine Communication: The Yorùbá Example". An Inaugural Lecture, 2015/2016, University of Ìbàdàn, Ibadan (Nigeria),2016

Ọlatunji, Olatunji. *Features of Yorùbá Oral poetry*: Ìbàdàn University Press, 1984.

Ọmọjọla, B. "Music and Dance" in *Culture and Performance*, ed. T. Fálọlá and Akíntúndé Akinyẹmi , Austin, Pan-African University Press, 2017.

Owolabi, Kola. "Noun-Noun Construction in Yorùbá, Language". Unpublished doctoral dissertation, University of Ìbàdàn, Ibadan (Nigeria), 1976.

Rowland, J. *Teach Yourself Yorùbá*. London: English University Press, 1969.

Ruwet, N. *An Introduction to Generative Grammar*: Amsterdam Gate Press, North-Holland, 1973.

Yule, G. *The Study of Language*: Cambridge University Press, 2007.

Yusuf, Ayo. "Lexical Morphology in Yorùbá Language Engineering". Unpublished doctoral dissertation, University of Lagos, Lagos (Nigeria), 2008.